# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 39. SATURDAY, April 7, 1923. Fourpence.



*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.



**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall (Customs Street,)* EKO






Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ Masini-aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Meji'a tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orișirisi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay.**

*(Macaulay's Household Dispensary.)*

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni opopo-nla (*Broad Street.*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakoregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Ka'awa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-erọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA,

Ọgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Ọlaurewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Şabu rẹ ni No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aşọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten.*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

WHAT IS MORE REFRESHI[NG] than a sound sleep on a com[fortable] Bed? or time-savi[ng] than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment [of] Brass Iron-Beds, Bedstea[ds] (new arrivals from German[y]) hand and Treadle-sewin[g] machines "Gritzner" is just [to] hand at Mr. Duro. Thomas' establishment 55, Massey S[t.] Lagos.

An early call at this addre[ss] for your selections will we[ll] reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW

---

KILO NGPE MI LỌ YI O? ORUN

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şẹşẹ de fun u pẹlu MAŞINI iranşọ ti a npe ni *Gritzner* ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati Ilu Jamani wa tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹnia Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

### JAGUN-JAGUN WỌ LU Ẹ F' ARA BA LẸ

Ọkọ ogun o ni opo-ẹfi mẹrin to de silẹ yi ninu ọsẹ to kọja lo sọ fun ni pe ọtọtọ ọgagun Gẹsi kan wa sibi ti a npe ni Rear Admiral BENTINCK.

Lati igbati o ti de ni ọkọ na ti nrọ agba ni agogo mẹsan alẹ lẹhin igbati ti Apapa ba ti dun tan ni agogo mẹjọ alẹ. Ọgagun na nlọ nkakiri gbogbo Ilu to wa labẹ Gẹsi lati mọ alafia wọn a gbọ pe o ti lọ si Ilu Aganyi, Gambe ati Saro ki o to de si arin wa nibi ẹkinni ti ọkọ ogun olopo-efin mẹrin ma kọ de ibi ni eyi.

### A BỌ O, AYI BI OWU.

Bishop G. A. Oke ti o ti lọ si ajo fun Ijẹ Church wọn larin awọn member rẹ ni Ilu Ikalẹ ati ibomiran lati ọsu kẹta wa de lọjọ Easter Monday; oru lo fi wọlu ni ọjọ na, Alafia kẹ de bi? Ṣe Ẹ ba'le l'alafia? Ẹ ku Ọba 'sin.

### OYE A MỌ NYIN LORI.

A o fi Alufa James Feyiṣara Ogunko ati Alufa Emanuel Ayọdele Salu jẹ oye Alufa kikun ti Ijọ ọmọ-ibilẹ (U.N.A.) lọ la ni Ile-isin [wọn Jehovah Shalom ni Agogo mẹsan isin arọ.

### ỌPẸLẸNGẸ ATI ONIPELE LỌ S' AJO

Awọn ọrẹ wa E. A. Alawọde ti Ile iṣẹ ilu (P.W.D.) ati W. S. Adeoye ti Ile iṣẹ ọkọ Ọba ni Apapa (*Marine*) lọ si Ibadan ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi fun Ipade nla ti Ijọ wọn *Baptist* ti a ti sọrọ rẹ ninu Iwe-irohin yi l'aipẹ.

### AWỌN IJỌ ONI DUNKUN OYINBO LỌ "ṢE BI ARIRA" NI IDIORO.

Kugu fọ ni Idioro ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi nigbati Ẹni-ọwọ *Archdeacon* T. A. J. Ogunbiyi mu awọn Ijọ rẹ lọ si Ile-isin kan ni Idioro ti o jẹ ẹka Ijọ wọn.

A gbọ pe nṣe ni onjẹ npe onjẹ ranṣẹ nibẹ lati arọ di alẹ, sara nyin ni yi o Ẹnyin Alakikanju Igbagbọ.

### Ẹ KU ṢẸ

A sọpẹ lọwọ Ẹni-ọwọ E K. Ajai-Ajagbe ti Ijọ Wesley ni Ereko fun Iwe-akanṣe to ṣe ni igba Ijiya Iku ati Ajinde Jesu ti a ṣe iranti rẹ ni lọlọyi: Koṣẹ ni Iwe na, o kun fun Ijimi ọrọ lọpọlọpọ. Tọrọ-tọrọ ni tita rẹ ni *Church* ki *Church*.

### ỌKU, AKURU YẸ JO.

A ki ọgbẹni Hamza Subairu kabọ Ilu Ọba to ti lọ lati Ọdun 1920 lati lọ kọ iṣẹ Iṣiro owo *Accountancy* fun Ilo owo Ọgbẹni W. A. Dawodu. Ọgbẹni na ba ọkọ Adda de ni ọjọ *Thursday* ọsẹ yi.

### OJO TO RỌ LO MU PẸTẸPẸTẸ WA.

Ojo ba nkan jẹ ni Easter *Monday* Ọdun ni fun awọn alariya ṣugbọn sibẹ-sibẹ a gbọ pe ṣiba ni Ebute Mẹta kun fun ọpọ enia ti wọn lọ jẹ faji nibẹ. Awọn to lọ s' okun ni *Easter Tuesday* ni "nkan ṣẹnu re" fun, nitoripe o gba fun wọn pupọ tobẹ ti pẹkẹ ko mi.

### NI IRANTI.

Emanuel Abiọdun Adejuwọn Olulẹ mi ọwọn ẹniti o fi aiye yi silẹ ni ijọ kẹtadilọgbọn oṣu *March*, 1922.

Olufẹ sun ko si ma simi gb' ori le aiya Olugbala rẹ Mo fẹ Ọ ṣugbọn Jesu fẹ ọ ju,
Sun-re! Sun-re!! Sun-re!!!

Olufẹ sun-re, kiṣe titi lai lẹhin igba diẹ awọn ẹni mimọ rẹ yo ma gbe pọ ni irẹpọ mimọ.
Sun-re! Sun-re!! Sun-re!!!

(MRS.) SUSANNAH ADEJUWỌN.

*Eko*, 27. 3. 23.

## ITAN ADELE, ỌBA EKO, LẸHIN TI O KURO LORI ITẸ.

Nigbati Ọba Adele kuro lori itẹ, o ti ilẹ yi lọ si Okun Igbologun lọdọ awọn enia rẹ; lati ibẹ, o lọ si Ijere, lati Ijere, o lọ si Işẹri Ọşun, lati ibẹ lo si wa tẹdo si Igbo Iloye, nibiti o gbe bẹrẹ işẹ agbẹ, o si nroko; o pẹ ninu igbo yi, nwọn a si ma pe oko na ni Oko Adele titi di oni. Lẹhin ti o kuro ninu Igbo Iloye, o lọ si Ado, şugbọn awọn ara Ado ko fẹ lati gba a si ilu wọn; nwọn si lọ wadi rẹ wo lọdọ Oduduwa orişa wọn. Orişa na si wi fun wọn pe, alejo on ni, ki nwọn jẹ ki o wọ ilu. Ọba Adele gbe to iwón ọdun mẹwa ni Ado, o si bi ọmọ ọkunrin ati obinrin nibẹ. Nigbati o wa ni Ado, ọkan ninu awọn Ojoye Agbadarigi ti njẹ Pọsu Awọnpa ranşẹ si i pe, ki o ma bọ wa si Agbadarigi, nitori ti Ọba Adele ba awọn ara Agbadarigi tan. Şugbọn ninu awọn Ojoye Agbadarigi ko fẹ ẹ, nitorina, ọran na da ijagboro silẹ larin wọn, nwọn si le Ojoye kan ti njẹ Akran, ati awẹn Ojoye to pẹlu rẹ si ẹhin odi.

Nigbati Ọba Adele wa ni Agbadarigi, o gbe ogun lọ si Ajaşẹ. O ni Akikanju Balogun kan ti njẹ Bobani; ẹniti o ba wọn ja li Ajaşẹ pupọ. Lati Ajaşẹ, o lọ si Iso, o si rekọja lọ si Iganvi ati Afọtonu, o gbe ogun si wọn, o si le wọn kuro ni ilu; lẹhin na o pada wa si Agbadarigi, o si jẹ oriki mọ awọn ilu ti o ti şẹgun wọn lara, wipe,—

"Emi a-dakan-lukan,
Emi a-fi-ija-lọ-ọmọ-Arada,
Mo jare Arada tan, mo jare Eko,
Ajibosun, a-fi-ọran-gbogbo-jare-jare,
Mo pa Hunsu, mo jare Hunsu,
Tani ọmọ onikoko-loju nfi oju di?
Emi a-pa-Egun-bi-ẹniti-ko-ba-Egun-tan."

Awọn ara Agbadarigi ko fi Ọba Adele şire; bi wọn ba si fẹ şe ohunkohun ni ilu, lati ọdọ rẹ ni aşẹ yio ti wa.

Lẹhin eyi, Ọba Ẹsilokun ku li Eko, awọn ara Eko si pe apejọ lati mu Ọba Adele wa ile; nwọn si ranşẹ si i li Agbadarigi lati wa bọ sinu oye rẹ. Nigbati Ọpolu, ọmọ Ọba obinrin ti işe ọmọ ologbe Ọba Ologun Kutere ri pe nwọn ranşẹ si Ọba Adele lati wa ile, o lọ si Iga, o si ranşẹ pe gbogbo awọn Ojoye pe ki nwọn wa pade on nibẹ, nitori ti on ni ọrọ lati ba wọn sọ. Gbogbo wọn si lọ, O si pa Pinişi olori awọn Ojoye, ati Fatolu Anikan-ba-Eko-ja, ati pupọ ninu awọn Ojoye yoku, nitori riranşẹ ti nwọn ranşẹ lọ pe Ọba Adele lati pada wa si ori itẹ rẹ.

Nigbati Ọba Adele de Eko, o gun si Okepa nigbati ara Eko si gbọ pe o gunlẹ si Okepa, nwọn di ọkọ-ajẹ, nwọn si nwa a kakiri li oju omi; nwọn nlu, nwọn njo, nwọn si nkunrin owe si Ọba Adele; nigba nwọn si fi oju kan a, nwọn fi ija fun u, nwọn si le lọ si Ibeşe Balogun. Ọba Adele si wa nibẹ fun iwọn oşu mẹta, lẹhin na, o si pada lọ si Agbadarigi; li akoko na ni awọn Ijẹbu ati Yoruba gbe ogun wa si Abẹokuta, ti nwọn si do si eti Odo Owiwi. Ogun yi ni awọn Ẹgba lara pupọ, tobẹ ti Şodẹkẹ fi ranşẹ si Ọba Adele li Agbadarigi lati wa şe iranlọwọ fun u ninu ogun na.

Ọba Adele si nbọ wa si Abẹokuta pẹlu awọn ogun rẹ. Nigbati o de Igbeji, awọn ara Igbeji ko fẹ ki o kọja ni ilu wọn; Ọba Adele bẹ wọn şugbọn nwọn ko, nwọn si fi ija fun u; o si do ti ilu wọn. Ọba Adele si şe ara rẹ bi obinrin, o bọ si ẹhin odi, o si ndin akara ogun; gbogbo awọn dankare ogun a' si ma wa yan akara lọwọ rẹ, şugbọn nwọn ko mọ ọ. Li ọjọ kan, Erelu Igbeji, ẹniti o kọ fun u lati kọja ni ilu rẹ şe ẹbọ kan, o si gbe lọ si ẹhin odi nibiti Ọba Adele ndin akara, şugbọn ko mọ pe Ọba Adele ni; o si fi Ọba Adele re nibẹ li ẹrinmẹta pe, "Aiya Adele, wa gba ẹbọ yi o." Bi o ti nwi li ẹkọkan bẹni Adele nwipe, "a şẹ!" nibiti o joko si ti ndin akara. Nigbati o si npada lọ si ilu, Ọba Adele pe e, o si fun li akara nla mẹta. Erelu dupẹ lọwọ rẹ, o si wi fun u pe, Adele ko fi ọkan ilu balẹ; lẹhin eyi, o si lọ si ile. Adele si dide nibiti o ndin akara, o lọ si ibudo rẹ, o si sọ fun Bobani, olori ogun rẹ pe, ọwọ yio tẹ Erelu Igbeji li ọjọ keji; o si paşẹ fun wọn pe ki nwọn gbẹ igi ti nwọn yio fi ga a silẹ. Nigbati o si di owuro ọjọ keji, bi nwọn ti joko ti nwọn nsọrọ, bẹni Erelu yọ si wọn, Ọba Adele si paşẹ fun Balogun rẹ pe ki o mu u; nwọn si pa Erelu Igbeji; lẹhin eyi, nwọn gbe ogun si Igbeji, nwọn si fọ ọ. Ọba Adele si fi Igbeji jẹ oriki pe,—

"Mo fọ Igbeji, mo jare Igbeji,
Tani Erelu nfi oju di?"

Nigbati o si dide ni Igbeji, o fẹ lati kọja ni Ilobi, awọn ara Ilobi ko fẹ, nwọn si fun ni ija; o si ba wọn ja, o si fọ Ilobi, Iwoye, ati Ilaro, o si jẹ oriki mọ wọn lara pe,—

"Mo ja Iwoye tan,
Mo gba arakun Ilobi,
Emi Ọba ti njagun pa eti Yẹwa."

Nigbẹhin-gbehin, lẹhin ti Ọba Adele ti jagun titi lona, o de Abẹokuta. Ki o to wọ ilu, Şodẹkẹ ti gbọ, o si yara lọ pade rẹ li ọna, o si sọ fun u bi ogun ti gbona fun wọn to. Nigbati nwọn de ile, Ọba Adele sọ fun Şodẹkẹ pe, ki o lọ

wa ọgẹdẹ agbagba ati epo pupọ wa fun on. Ṣọdẹkẹ si mu nwọn wa fun u. Ọba Adele si lọ si ibudo-ogun awọn Ijẹbu ati Yoruba, o si ṣe ara rẹ bi obinrin gẹgẹ bi o ti ṣe ni Igbeji o si ndin ipekere fun wọn nibẹ; gbogbo awọn ọmọ-ogun Ijẹbu ati Yoruba si nra ipekere lọwọ rẹ, ipekere dun mọ wọn lẹnu, nwọn ko si mọ pe edi Ọba Adele ni nwọn njẹ.

*Iwe-irohin Eko 1889.*

---

**Report of the First Parochial Anniversary of St. Paul's Church, Breadfruit.**

To the Editor
"Eko Akete"

Sir,

Above is the tittle of a new publication recently issued under the auspices of St. Paul's Church's Authorities. It is the first of its kind in the history of the Church and reflects much credit on the organizing ability of the Pastor of the Church, the Venerable Archdeacon Thos. A. J. Ogunbiyi whose creative genius, magnetic influence and force and indomitable energy have become proverbial in the Christian world of Nigeria.

To aver that the able person is highly esteemed by his Parishioners is to reiterate a well known fact but the meaning of the word "Beast of Burden" which he employs in referring to himself in a letter dated 29th March, 1922 to his congregation published in a page opposite his own photograph in the Reports really passeth our understanding. We do not think it is a distinction to be a "Beast of Burden" and ill would appear to be the fate of those Parishioners whose Pastors are a source of burden to them. But perhaps the reverend gentleman will illustrate his meaning and thus dispel a thick cloud of gross misunderstanding. We know the Archdeacon very well and are well aware of his kind and sympathetic disposition towards all and sundry.

The English Edition of the Report under review was ably compiled by Mr. A. E. Norman Williams who acquitted himself of the task in a manner quite complimentary to his ripe intelligence. It is not a Voluminous document and though concise, the brevity is not maintained at the expense of non reporting any event that really matters. Practically the whole ground is covered and we admire Mr. Williams' dexterity and diplomatic allusion to Rev. C. E. Doherty. B. A.

The People's Warden, Mr. E. W. George who was responsible for the translation of the work into Yoruba language has contributed his own quota towards the success of the undertaking and the popularity that awaits the Brochure. And although Mr. George's work in this respect is devoid of originality the thanks and encomiums of the Church are no less due to him. Translation, after all, is not such an easy task as many an inexperienced is apt to think and to be able to sufficiently realize the difficulty which it involves, one only has to remember the never-to-beforgotten-incident of an old celebrated African Catechist who, whilst interpreting an English Sermon to one of the Anglican Church's Congregation here some years ago, rendered the meaning of "Saul, Saul, why persecuted thou me." as "Iyo, Iyo, kilose ti enyin ko dun obe"? (Beware of laughter.)

On Page 6 of the Report is published a Programme of the first Parochial Anniversary Meeting, held on May 2nd, 1922, in the School Room, at 7 p.m. under the Presidency of J. T. N. Cole Esq: B.L. with a Resolution to continue or celebrate future Anniversaries of the Meeting. If this Parochial Anniversary Meeting was a fully representative one as it ought to be, then the Resolution of the Parish Girl's Own Public Meeting held on May 5th, 1922, on the same subject is as useless as the fifth wheel of a Coach unless the promoters of the latter Meeting are a seperate body who do not form part and parcel of the whole Parishioners which the former meeting represented and consequently the decision of the one is not valid without the express sanction and ratification of the other.

In Page 10, the compiler Mr. A. E. Norman williams tells us that "This Report will be based upon the work done from the 1st day of April 1921, to the 31st day of March, 1922, and in Page 12 of the Report we find a list of appointments made during the period. But on comparison, the list is not in conformity with the supposed photogrphs of the officers appointed during this period. Fancy, in Page 20 we find Mr. Wey usurping the right of Mr. A. E. Norman Williams as Parochial Secretary and the latter occupying Mr. O. H. Williams, the Paster's Warden's room.

The same remarks apply to other exhibits in the Pamphlet and this irregularity accounts for non appearance of men like Messrs. J. F. Coker, James Bailey and G. O. Awoliyi in the group photograph of the Parochial Committee Members. The Compiler owes each of these men an unquaified apology. And, to some extent, we think the non inclusion of the audited financial return of the Church in the Report is a serious omission, unless the Auditors Messrs C. A. J. Williams and E. A. O. Bright had not properly discharged their duties and any delinquency on their part does not appear to have been the case.

On the whole the Report is satisfactory, and we congratulate all concerned.

Yours Truly,
Rock of Ages.
*April 3, 1923.*

---

**CHANGE OF NAME.**

I Michael Adol Martins formerly known and addressed as above, beg to inform the public in general that from and after 1st day of April, 1923, all letters documents, should be addressed to me as ADEYẸMI ỌṢONARIWO.

Any letters or documents, bearing the former name before this date remain valid.

ADEYẸMI ỌṢONARIWO.

**EKO AKETE:**

Eko, Saturday, April 7, 1923.

## ẸKỌ GBE NI NIYI, ỌGBỌN NGBE NI GA GÒGÒRÒ

Bayi ni Ṣobọ Aro-bi-odu ọkan ninu awọn Akewi Ẹgba wi nigbati o nsọ ti anfani to wa ninu Iwe-kikọ, ko si si ẹniti o jẹ ko iyan Ẹkọ to ye kõro (*Sound Education*) kere, papa ni aiye isisiyi: nitorina lo ṣe tọ ti o si yẹ gidigidi lati sapa lọpọlọpọ ki a le ni anfani nla yi, tabi ki a fi fun awọn ọmọ wa.

Akoko kan ti wa ri, ti o jẹ pe pupọ ninu awon ara wa ki nbikita fun irufẹ nkan iyebiye yi, ti o si jẹ ede wa lati ma sọ pe ẹniti ko mọ'we njẹun, iwe wo ni Lagbaja tabi Tẹmado mọ ti nwọn fi di clowo? Ṣugbọn irufẹ ede bẹ ko wọpọ mọ ni ode isisiyi: ṣaṣa ni iṣẹ to wa ti ko fẹ oye iwe mimọ ibaṣe diẹ: ẹnyin ẹ wo Iṣẹ-aranṣọ: bi enia ko ba loye Iwòn-mimọ (*Tape-rule*) bi oluwarẹ ba daṣọ fun ni, yio dabi agbawọ ẹwu, bi ko fun ọ l'ẹsẹ a ṣo ọ: ẹwẹ, irufẹ aṣọ alugbagba bẹ le jẹ ki a pe ẹniti o ba wọ ọ ni Alapo'yọ õ le sure!!! gẹgẹ bẹ si ni Iṣẹ-Gbẹnagbẹna pẹlu: a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti Iṣẹ Akọwe mọ, eyi papa nfẹ iwe-mimọ faufau, bi bẹkọ oluwarẹ yio "bo'lẹ."

Agbara ti pupọ enia nsa larin wa nisisiyi lati ma lọ si Ile-Ẹkọ alẹ ti awọn alakikanju "Kiriyo" kan da silẹ laipẹ ni igboro wa fun awọn to ba tubọ nfẹ ni oye si ninu iwe wọn fihan gba-ngba pe ko tun si ẹniti o fẹ joye "Akọwe Alagbon" mọ, ẹniti a sọ pe "ko mọ'we," ti "Adiṣọni to gbẹkẹle ko to dakọ mu!!!"

Laisi ani-ani ko le jẹ iyalẹnu fun ni lati ri pe irufẹ awọn ẹniti o ntiraka bayi ntẹ siwaju ninu iṣẹ wọn: ohun ti o ku ki a ni larin wa ni Ẹgbẹ ti yio ma ṣe ãyan Kika-Iwe pọ (*Literary Societies,*) eyi wọpọ ni Ilu Aganyin ati ni Saro, ara ẹ jẹ ki a ji giri si Ẹkọ-Iwe to jire ni ilu wa yi, o si yẹ ki a mọ nigbakugba pe ki ọtun wẹ osi, ki osi wẹ ọtun, ni ọwọ fi nmọ. (Owe ni o!)

---

## ỌBA l'E ONILU Ò JO?

Prof. Adeoye Deniga, npete lagbara Oluwa lati sọrọ Asọye Itan ati Iṣẹ diẹ ni ede wa ti Awọn Ẹni-nla wa wọnyi:—

| | |
|---|---|
| Bishop Johnson | Dr. Blyden |
| Mohammed Shitta | Alufa M. L. Stone |

Ni Ile-iwe Breadfruit ni ọjọ *Tuesday* (ọjọ mẹrin oni) ọjọ kẹwa oṣu yi ni agogo mẹfa-abọ alẹ.

A o ṣe Aworan awọn Ẹni-nla na pẹlu, a o si kọ orin Ilẹ wa ti Professor na ti ṣe fun ọjọ na. Kọbọ kọkan ni a nta. Ẹnikẹni to ba fẹ wa, yio ju Owo Fadaka bi Tọrọ, Sisi, tabi Ṣile, sinu awo ko to wọle.

Ara Ilu ati Ẹnyin Ọrẹ Ẹ ma ṣai wa sibi ere na; ṣeranwo ni yio jẹ. Apọnrọn yio ma dun kikan lalẹ ọjọ na. Dokita Oguntọla Ṣapara ni yio ṣe Alaga Ipade na.

A nireti pe Ile yio kun Ọna yio bò, Ẹkan loṣu la o ma sọ Asọye yi. Ilẹ a rọ lọjọ yi!!!

Ọgbẹni Dada Adeshigbin ni Alaworan na.

---

### SORINOLU'S GRAMMAR SCHOOL.

*The first ever Established in Abeokuta and Jebu-Ode.*

To the Editor of "Eko Akete."

Dear Sir,—My attention has been called to a portion of a "Letter from Abẹokuta" of the 1st instant, published by your contemporary, the *African Messenger*, detailing the "circumstances" causing the tragical death of my Grammar School, Iporo-Ake, Abẹokuta, established January 22, 1906 on July 1908.

The writer seems to be a man behind the scene, having specially named the eminent men unrighteously engaged in the crusade to have included the Rt. Rev. Bishop Herbert Tugwell the then diocesan, the Oke-ọna (Ikereku) Pastor, and late Rev. E. W. George, of Iporo-Ake, and for no other reason (the writer says)

# SINGER! SINGER!! SINGER!!!




Kinla! Tiwa ki nṣe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin oriṣiriṣi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI ẸDINWO NLNLA TI A ṢE

inu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRIN-IṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a ̣nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

---

Wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun patakii ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri oriṣiriṣi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tun gbogbo Ẹrọ Iranṣọ 'SINGER' ṣe nigbakugba l'ọfẹ ibaṣepe a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Popo nla l'eko nibiti 'Ẹrọ Oyibiri' nl'agogo.

hone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*


---


## *ILE EGBOGI TITUN.*

irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a ṣi Ṣọbu Egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Ṣọbu yi jẹ ẹka Ṣọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ojulowo pọ nibẹ. Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

than an alleged opinion of mine on marriage which is more of a social than an ecclesiastical concern. I am simply amused to read the story; and I would not have replied had he not concluded by saying the Anglicans had *re-established* at Igbein where their Grammar School once stood in 1867.

Now, Sir, there was no Grammar School at Igbein then but a Divinity school to train up pastors, evangelists, and teachers for evangelizing the Ẹgbas and the surroundings. It would be absurd to start up a Grammar School in a yet unevangelised land as Abeokuta was in 1867. With difficulty, much coaxing and bribing the Day and Infant scholars were then found. The Institute suffered in the outbreak of 1867, subsequently removed to Lagos, and thence to Ọyọ in the 80's where it still stands a Divinity school or college to this very day. Therefore it is a veritable fact that my humble effort of January 22, 1906, so sorely persecuted by the mighty ones for no just course, has been the first ever established Grammar School in Abẹokuta. A branch of this also was the first ever planted at Jẹt u Ode.

Thanking you for space allowed,

I am,

Yours faithfully,

Ariyọ Ṣorinolu
*Principal & Proprietor*

Iporo-Ake,
Abẹokuta,
*26th March 1923.*

## "IDARAYA FUN AWỌN ỌMỌDE."

Awọn ti o ba ma wa, ki o ra iwe yi ki o si kọ ẹsẹ ti o gbẹhin (ti o ma dara pẹlu awọn ti o wa nibẹ) si, ki o si fi ranṣẹ si "B.O" c/o Editor "Eko Akete." Bi o ba fẹ o le ra iye ti o ba wun ọ ki o si kọ iye ti o ba fẹ si inu wọn ṣugbọn esi kankan ni lati ni *Coupon* kankan orukọ awọn ti o ba jagun molu yio han ni iwe yi ti ijọ kerinla oṣu yi *14th April 1923.*

**Akiyesi**—Gbogbo esi ni lati de ọwọ wa ni *Friday* Jimọ ọjọ kẹtala *13th April* oṣu yi, ki o si fi tọrọ (3d) ranṣẹ pẹlu esi kankan.

COUPON.

Mo ti ka gbogbo ọrọ ti o wa ni oke iwe "Iwe irohin yi jẹ iwe irohin ti ede Yoruba o si wa fun ire ati lati ma sọ irohin ti Eko o yẹ ki ama ra, ki a si ma ka

.......................................................

Orukọ.................................................

Ibiti ongbe...........................................

.......................................................

Esi ti o ba dara-ju oluwa rẹ a gba ṣile meji ab[…]
Eyi ti o ba tẹle „ „ „ kan „
Eyi ti o ba tun tẹle eyi „ „ „ „


**All for Bicycles and Motors**

Ask for KADUNA STORE
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Bead edge

do. do.

The above Tyres are specially for Rud[…] withworth and German Cycles and have complete workshop for repairing all kinds of machinery. Send all [...] repairs' Bicycles, Motors, Sewing machin[…] Gramophone painting enamelling [...] soldering etc., to the Properi[…] the undermentioned address. All Bi[…] spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Stre[…]
or at Workshop 81, Ọdun[…]
Lagos.

*Telegram Address:*—KADUNA STORE
81, Ọdunfa Street,
Lagos.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kōtu, l' Eko.

## WANTED.

Reliable Agents required for sale of English Ready-made COFFINS, at Lagos Abẹokuta, Ibadan and Jẹbu-Ode.

For Terms and Conditions,

Apply to A. BANK. ANTHONY,

137, Tokunbọ Street, Lagos.

## A TOTO, O!

A nfẹ Enia "GIRIKI" ti yio ṣe oju Ọgbẹni A. BANK ANTHONY ni Eko, Abẹokuta, Ibadan, tabi Jẹbu-Ode, lati ma a awọn POSI-meremere, ti o ti ilu Ọba wa lati Ọgbẹni Oniṣowo na.

Ẹniti o ba nfẹ, ki o kowe si Ọgbẹni na. ni adugbo rẹ 137 Ita Tokunbọ l'Eko.

## O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, ile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. ti ọja rẹ lọ si bẹ

## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ̀ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*

c/o Anfani Motors

The Marina Lagos.

## "KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orişirişi ko ni egbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

## IYA AFIN SẠBINA BỌLAJOKO.

Ti No. 39. Ita Matinin jẹ ẹniti o gbaşẹ ati ma ta orişirişi ỌTI o si nta awọn nkan Ipanu ni Ṣabu rẹ yi.

Ẹ lọ ke si i, Wàrà-ṣẹṣa ni ọja rẹ, owo wọn si mọ-ni-wọn ti makunnu.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING) Masses Isin Aro,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9 30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.— | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | Bro. C. W F. Shaw |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | | |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. Supt. D. A. Hughes |
| 7 p.m. | Odination Service | Rev. M. B. Newton |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 7 p.m. | do. | Bro. M. I. O. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. B. Coker |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. A. T. Fayan |
| 6.30 p.m. | do. | N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. A. T. Iroko |
| 4 p.m. | | Rev. I. O. Oyekunle |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Bro. S. M. Phillips |
| 4 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | Bro. John Apena |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Pastor A. Adedeji Iṣola |
| 7 p.m. | | do. |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbe

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. A. (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m —Evensong and Sermon The Bishop of L.

SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. in the Streets.

---


SIMENTI NYAJU!!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Ma... L' Eko ni ojulowo *BIRIKI* fun tita fun ... owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn BIRI... yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri nyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

---

W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WA!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSO... ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu Al... MASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọpọ...

Ni Ile-iwo orişirişi ọja ti
Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER
Oniṣowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjọ, leti Ita William
lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun...
ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi...
Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafọ ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ

### Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Işẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloyẹ Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wọnyi ti o şẹşẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọşẹ rẹ, Egbogi Işaka, Jẹdijẹdi. Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kinişa, Egbogi Inu riru iwaşu, ati fun ọkunrin pelu, egbogi ki ara ọkunrin le giri (ko ma ye ẹ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le darukọ tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpokuoyoku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o,

"Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ.".

Joshua O. Ade: Craig,
*Alabojuto.*

116 Great Bridge Street,
Ita Onikoyi, Idumota,
Lagos.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aşoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni Vidal R. Cole.

---


**WHY LOOKING SAD. ?**

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous postration or loss of memory why don't you use Muiracithin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthenia etc., etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine, the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills, and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajenifuja" Store No. 109 & 111, Broad Street.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

---

**FIRST CLASS TONSORIAL ARTIST.**

Mr. A. L. KOSỌKỌ the well-known Barber late of Customs Street, Lagos, begs leave to inform his many clients of his new Establishment at 135, Victoria Road, this City, where prompt attendance will be accorded them as heretofore.

Razors, Combs, Perfumes, etc, are also on sale at prices to suit everybody.

Call or send; warm wellcome to all.


NOTICE.

When replying advertisers, ple... mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ... Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iw... Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---


**First Class Dressmaki...**

Mrs. Abraham Asharr trained... begs to offer her professional s... the public.

Latest modes at moderat... satisfaction gauranteed. Call at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

**PAGIDARI!**

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wosi ... elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹşọ ti o si nta ... oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na ... nşe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, ... kan, şisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan onirunru aisan, ... olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan n... mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin işẹ ati Egbogi ti ... aworan wa nibẹ ni ọpọku yo...

Oniru-nru wosiw... bere ohun-ko-l...

O ngbero ... ti a npe ni ... a npe ni ... le fi iyẹ-owo Iduumagbo.

Şorọ... to ba fẹ ransẹ

...wọn si nransẹ *Cement* ...orişirişi ọja

...ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn ...OJUBA.

## ...E LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWO."

Sole-eather tanned in a most modern style ad Upper-Leather prepared in all colou namely:—Black, White, Red, Yell and Green, are obtainable at very che prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ a ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams* :—Alawọbata, Eko.



29, Oripasan Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

... I have many years' experience in ... of Plain Window to any ... cleaning or white ... colour etc., ... new, by Vanish ... to Paint House ... address

9 ...
6.30 p ...
7.30 a.m. th ...
7 p.m.



## Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o ṣi "Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọlọdina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m     2 p.m de 8 p.m
Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m
Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,
Ogun rẹ jire.



## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


... YS, 20, Market Street, Lagos, and Published by ... reet, Lagos, Writer and Lecturer.